COVID-19 VACCINE
Public Health Advice

# Lẹhin ti o gba **Ajvsara Moderna** COVID-19

O ṣeun fun aabo ara rẹ ati awxn miiran nipa gbigba ajẹsara naa. Bayi ti o ti ni ajẹsara rẹ, a rọ ọ lati ka iwe yii daradara, ki o le mọ bi ilara re o ṣe ri laaarin ọjọ diẹ ti nbo ati ibiti o ti le gba alaye diẹ sii.Ka iwe pelebe alaye ajesara COVID-19 ti a fun ọ nibi ajesara naa. A tun n fun ọ ni akọsilẹ ti ajesara rẹ loni.
**Da kun tọju kaadi iforukọsilẹ lailewu.**

**Kini o le ṣẹlẹ ni iwọyi ọjọ diẹ ti nbo?**

Diẹ ninu awọn ti o gba ajesara ti o gba ni oni:

- ni irẹlẹ, wiwu, pupa ati / abi yiyun ni apa ibiti wọn ti gba abẹrẹ ajesara naa
- Irira
- ni orififo
- Awọn iṣan kekere ti o wa l'abẹ apa ibiti wọn ti ni abẹrẹ maa wu
- ni irora iṣan
- ni irora irikerike
- ni ríru tabi eebi
- ni iba (iwọn otutu 38 Celsius abi to ju bee lo).

Bii gbogbo awọn ajesara, o le ṣe ijabọ awọn ipa ẹgbẹ ti o fura si Alaṣẹ Iṣakoso awọn Ọja Iwosan (HPRA). Lati ṣe ijabọ awọn ipa ẹgbẹ si ajesara COVID-19, Dakun Lọ si **www.hpra.ie/report**

**Ti mo ba ni iba ati irora nkọ?**

Ti o ba ni iba abi o ni irora, o le mu paracetamol abi ibuprofen lati ṣe iranlọwọ. Sibẹsibẹ, ti iba rẹ ba pẹ ju wakati mejidinlọgọta lọ abi ti o ba wa ni aibalẹ ara, Da kun wa imọran iṣoogun. Maṣe mu ibuprofen ti o ba loyun.

**Ṣe mo nilo lati ṣe ohunkohun ṣaaju gbigba iwọn lilo keji ti ajesara naa?**
Nigbati o ba ti gba iwọn ti akọkọ rẹ ati ikẹhin ti ajesara, Da kun sọ fun ẹgbẹ ajesara ti ayipada eyikeyi ba ti wa ninu itan iṣoogun rẹ.

**Mu kaadi iforukọsilẹ ajesara rẹ wa pẹlu rẹ nigbati o nlo gba iwọn lilo keji**

Eyi ti waa gba ni ọjọ mẹrindinlọgbọn si isisinyii (ọsẹ mẹrin).

**Awọn ihinrere**

Gbigba ajesara COVID-19 yẹ ki o daabobo ọ lọwọ ilolu nla ti COVID-19.

Ajẹsara yii a kọ eto ara rẹ lati daabo bo ọ lọwọ awọn aisan. O jẹ ailewu pupọ fun eto ara rẹ lati kọ ẹkọ yii nipasẹ ajesara ju nipa gbigba COVID-19.

**A ṣi nkọ ẹkọ**

O ma gba ọjọ mẹrinla lẹhin ti o gba iwọn lilo keji fun ọ lati ṣiṣẹ.

Aye kekere wa lati tun ni COVID-19 bi o tile je pe ti o ni ajesara naa. A ko mọ dajudaju ti nini ajesara naa ba da ọ duro lati tan ọlọjẹ naa kaakiri si awọn miiran, nitorinaa o gbọdọ tẹsiwaju lati tẹle imọran ilera gbogbogbo:

- tẹle awọn itọnisọna jijin ti awujọ
  (ni mita meji yato si awọn miiran nibiti o ti ṣee ṣe)
- wo ibora oju
- máa ṣọn ọwọ́ rẹ déédéé.

**Ṣe o ni ibeere kan?**
Ti o ko ba ni iyemeji nipa ohunkohun, abi ni ibeere eyikeyi nipa ajesara COVID-19 Da kun beere lowo awọn ti o fun ọ ni ajesara rẹ loni.

Lọ si **www.hse.ie/covid19vaccine** fun alaye diẹ sii lori ajesara COVID-19.

**Awọn ipa ẹgbẹ**
Da kun jabo eyikeyi awọn ipa ẹgbẹ yi fun HPRA ni **www.hpra.ie/report**

Atejade ti HSE ni ọjọ keji osu Keji [February] 2021.

Ẹya 2.

Rialtas na hÉireann
Government of Ireland